# AKOSO IJOBA ORE ARA ILU

**(IJOBA TO N LEPA MIMU AYE DERUN)**

**ELEYI NI**

**MAJEMU MI FUN AWON ENIYAN MI NI**

**IPINLE OSUN**

**EYI NI MO GBEKALE LORI ILANA**

**MEFA OTOOTO**

**RAUFU ADESOJI AREGBESOLA**

## Majemu mi pelu awon eniyan mi ni Ipinle Osun,

## Ile orisun omi- Land of the Living Spring

Ipinnu awon baba nla wa ni osu kesan-an odun 1886 ni ibudo ogun (KIRIJI) to nbe ni agbede meji Okemesi ati Igbajo ni ki alaafia, ilosiwaju ati ibukun joba larin awon omo Oduduwa. Bi a ba ranti akoso ijoba oloselu awarawa lo fi idi remi ni odun 1962 ni igba ti awon ologun gbajoba, ti gbogbo ilu wa di rudu-rudu, titi to fi di oni olonii.

Ni bayii ti idibo gbogbogboo ti odun yi 2007 wole de a si tun n beni

1) Eto eni ti won fi n du ni lenu oselu
2) Didenu kole oro-aje, ati
3) Inu foo, edo foo, aisi ibale okan.

Awon idi Pataki niyi ti mo fi fe du ipo Gomina Ipinle Osun. Ete akoso ijoba temi, kii se ti awon ojelu ajegudu-jera to ti gbade leyin ti baba wa Oloye Obafemi Awolowo ti kuro lori aleefa.

Akoso ijoba to wa lode bayii, lo kun fun imotara-eni nikan, tenbelekun, airije-rimu ati aisi aabo to peye laarin ilu.

Ohun ti emi n lepa ni ijoba to ma a fi teru tomo, atonile atalejo lokan bale lona ti alaafia yoo fi joba, ti awon eniyan wa yoo fi maa gbadun aye won laisi ifoya Kankan, ti gbogbo mutumuwa yoo fi maa rihun je labe akoso ijoba ore ara ilu.

**Awon ilana mefa wonyi ni mo kanle gbe dide gege bi ohun ti mo nigbagbo ninu re gidi fun aseyori akoso ijoba mi eyi ti mo ma mu gbo loju mejeeji.**

## ILANA MEFA OTOOTO FUN ASEYORI

ki a le ise sigbo(kajola)

ki ebi ye pa aye( karije)

ki ise ati oro pada si arin wa ( Karise, Karita)

ki ale arun wole ( Karaole)

Ka keko to se anfani

ki aye dara fun gbogbgo wa (Kodara)

**KI A LE ISE SIGBO (KAJOLA)**

**Isipaya wa: Ki Osogbo di oja nla ti agbaye fun tita ati rira.**

Aini eto liana oro-aje ti yoo ran ilu lowo lo ti sakoba fun akitiyan awon eniyan wa ni ipinle Osun, ti sise-sise wa fi dabi ole.

Akoso Ijoba awarawa ti egbe oselu ACN labe ase Raufu Aregbesola ni yoo ta ise owo ilu ji pepe ti yoo si mu ki oro ilu padabo sipo kara-kata ti won mo wa mo niluu Osogbo ati jake-jado Ipinle Osun. A o so isowo dotun.

Atileyin ati igbelaruge to daju ni yoo wa fun enikeni to ba fe da ise sile.

A o so Osogbo di oja agbaye ti awon eniyan yoo ma ra oja ni iye kan na ti won n ta ni awon oja nla kaakiri.

**ERONGBA ISU NA-OWO**

A o ri i pe, owo to n wole sapo ijoba po si I, atipe ko si inakunaa lori owo to n ba wole sapo Ijoba ipinle Osun, nipa

- Riri i pe eto isuna owo Ijoba wa larowoto awon ara ilu, atipe a maa kappa inakunaa nibikibi ti a ba powo Ijoba mo si.
- Siseto inawo to moyanlori. Riri-i-daju pe a o na owo Ijoba lona aito.
- A o maa lo owo Ijoba fun ise idagbasoke ilu.

**Koko ohun ti ojuse Ijoba wa maa lepa ni aidara-de owo to n wole sapo Ijoba Ipinle lati odo Ijoba apapo.**

**KI EBI YE PA AYE (KARIJE)**

**ISE AGBE ATI IPESE OUNJE**

**Isipaya wa: A o fopin si airije-rimu ni Ipinle Osun, a o si mu ise agbe lokundundun nipa pipese ounje lajeyo ati ajeseku.**

Gbogbo agbe ni yoo ma ri oun ogbin won ta

Agbe ko ni se ase danu mo

Nitori a o ma ran awon agbe lowo ni ona ki onje le po repete, pipa awon ere oko mo fun igba pipe, ati fifi aaye gba agbe lati ma ta awon ere oko won latajere.

Lati mu ki awon anfaani wonyi de arowoto awon ara ilu, akoso ijoba labe ase Raufu Aregbesola yoo:

- Pese awon opopona sogbe-dilu fun oko lati rin papa awon igberiko
- Kiko aba ipamo ounje tabi ere oko si awon ekun igberiko
- Pipa nnkan ogbin ounje mo fun igba pipe

- Siso ere oko di ounje
- Ipese ina oba ti a mo si ele ntiriki ati omi-ero sawon ekun igberiko.

**Igi Owo**

- Koriya wa fun ise agbe aladaa-nla nipa gbingbin awon ere oko igi owo bii ope ti yoo je igi leyin ogba fun oro-aje ise agbe ni ipinle Osun.
- A ri i pe won o ma re awon agbe je nipa diliyele oja ere-oko won.
- A o ripe awon agbe wa ni ipin to po ninu tita si awon oja ounje [egberun lona egberun lona egberun (bilioni) naira] to wa ni awon Ipinle to yi Osun ka
- Ri i pe a je okunfa fun igbelaruge ati idagbasoke ise isowo keekeeke nipa sise amulo awon ohun alumoni ti Oluwa fi sike wa ni Ipinle Osun.

**KI ISE ATI ORO PADA SI ARIN WA (KARISE-KARITA)**

GBIGBOGUNTI AIRISE-SE

Ipinnu pe ko ni si ipadanu ise, ise yo po repete.

Akikanju ise ati onisuru ni awa omo Ipinle Osun. A ki se ole rara, awon eto gba lowo meri, ti ijoba PDP lo je ki akinkanju dabi ole.

Gege bi eto ijoba tiwa to yato si ti awon ojelu, emi omo yin Raufu Aregbesola se majemu pelu eyin omo rere Ipinle Osun lagbara Olorun pe Ijoba wa yoo pese ise fun oke kana won eniyan ti ko nise lapa, laarin ogorun ojo ti a ba gori aleefa.

A o sanra lati gba awon osise egberun marun-un pada senu ise lara awon ti won feyin won ti, sugbon ti won tun fe sise. Bakan naa ni akoso Ijoba wa yoo satileyin fun enikeni to ba fe da ise sile.

A o da ile eko ti a o ti ma ko awon eeyan ni eko ati ise ti won yoo le fi sise ati gbe aye iderun (akedemi aye). Meta ile eko yi ni a o da sile ni Ipinle Osun fun omode ati agbalagba.

Ijoba yo da ibi ti eni to nwase yo ma pade awon to ngba ni sise, fun awon to ba jade ni ile iwe eko ise owo ati aye ti a o da sile.

**ATUNTO ISE OBA**

Atunto wa ma a mu ayipada rere wa fun ise oba ni, lona ti awon osise yoo fi tubo nifee si ise-ona siwaju si i.

A o ri i pe a n san awon owo ajemonu awon osise-ona deede, bee ni owo osu lasiko-lasiko pelu agbende awon ami eye idanilola lodo odun, eyi ti yoo mu ki koriya wa fawon osise-ona lati le e ma fi gbogbo ara sise.

Afikun si owo osu awon osise oba ati igbega ni yoo ma a waye lasiko to ye.

Idanilekoo abele ati toke-okun yoo tun wa fun awon osise lati ri i pe, won goke agba lenu ise won.

Awon Oluko yoo ma a gba igbega lenu ise de ipo Akeko Agba yan-yan, ti a mo si Akowe Agba lati ma mojuto akoso awon ile iwe lawon elekun-jekun.

A o pese anfani lati di onile f'awon osise oba pelu ona ati ran won l'owo lati s'owo onje keekeeke, ti won a le ma se l'ayika ibugbe won.

**IRIN AJO-AFE:**

Ipinle Osun ni orisun ile Yoruba. Lateyinwa, ijoba ko ko'bi ara si idagbasoke ibi-igbafe wa to bo se ye ni Ipinle Osun, ni ona ti oro aje wa yoo fi po si.

**Ijoba wa yoo:**

- Mu idagbasoke to ja gaara ba eto oro ibi-igbafe Ipinle Osun
- Satunse to loorin si gbogan asa isenibaye Yoruba to wa n'ilu Ile-Ife nipa si so Ile-Ife di ibi ti gbogbo agbaye yoo ma wa.
- Fifun awon osere wa ni iwuri lati lo ebun ti Olorun fun won
- Lilepa ati gbigbe laruge awon Oba Alaye ati asiwaju laarin ilu.
- Sise atileyin fun awon Oba Alaye lati le se afihan awon ohun asa ati ise wa ti o le mu idagbasoke ba irinna afe, fun awon omo kaaro oojiire to wa ni ile ajeji bii Brazil, Cuba ati West Indies ( Amerika)

**OPOPONA**

**Isipaya wa: A o se opopona lati ilu de ilu ati igberiko de igberiko ni gbogbo Ipinle Osun.**

Nipa pipese ati ibojutoawon opopona wonyi awon odo ti ko nise lapa yoo rise se. Bi ona ba wa lati ilu kan de ekeji laisi wahala o daju pe oro-aje wa yoo gberu, eyi ti a ti setan lati mu lokundundun. Eyi yoo ran awon agbe wa lowo lati le ko ere oko won de ilu.

A o se idasile awon eka ti yoo maa mojuto atunse awon opopona wonyi laarin awon omo ara ilu.

**IGBOKE-GBODO-OKO:**

A o se eto igboke-gbodo oko nitori abo omo Ipinle Osun je wa logun.

A o ripe isele Ijamba oko din ku lawon oju opopona wa laarin osu mefa ti a ba gori aleefa.

A ma a se agbende eka kan ti yoo ma mojuto aabo emi loju popo gbogbo yika Ipinle Osun nipa lilo soke-sodo lori keke alupinpii awon agbofinro.

**IGBA-OTUN**

Bi o tile je pe akinkanju osise ti kii se ole tabi imele ni awon eniyan dudu, papaa julo awa eniyan Ipinle Osun sibe-sibe ko ti fi bee si ayipada kan to se e gbarale bii akitiyan awon oyinbo alawo funfun nile Europe, Japan, Malaysia, Korea ati China ti won ti pese igbesi aye alaafia fun awon eniyan won

A o tii mu oro ilepa imaye derun fawon eniyan wa lokun dundun to be se ye nipa iwadi atigbadegba, ati ofintoto fif imo kun imo eyi to le maye rorun fun wa. Awon Asiwaju wa ko tile bikita rar lori akitiyan alaafia ilu

Eyi ni emi ko faramo, nitori tokan-toakn ni ilepa allafia ilu fin je mi lokan. Bi eba dibo yin fun mi, ti efi ibo gbe mi sori aleefa geebi Gomina, emi Raufu Aregbesola ma sa agbara mi lati r ii pe

- Mo se eto ilaniloye to gbile lati trii pe awa eniyan Ipinle Osun dogba pelu awon eniyan agabye gbogbo
- Ri i daju pe a fi aaye gba awon to ba logbon lori lati da bira to ba wu won
- Mo fun eto eko laaye to se Pataki lati mu ki awon eniayn wa to gbangba su ninu oye pelu awon elegbe won kari aye
- A se idasile awon ojuko ekose-owo ti yoo mu ki awon eniyan wa ni imo to jinle lori ise owo ti won ba yanlaayo, lona ti ile wa Nigeria ko fi ni ma gbarale igi itayin mo lati China, Olomi osan lati Korea, baba lati Spain tabi Italy, taya lati Japan ati Faranse

**Mo maa so Ipinle Osun di ile oloraa nibi ti ise agbe yoo ti goke agba lagbara Olorun**

**ISE OKOWO**

Ona kan gboobi lati gbogun ti ise oun iya ni lati teramo ise okowo ipese awon eroja amuludun. Ijoba mi yoo

- Faaye gba idasile awon ileese olokowo keekeeke ati awon ileese okowo nla-nla, jake-jado ekun meteeta ti a pin Ipinle Osun si
- Pese awon ohun imuludun ti yoo gbe ise olokowo laruge, bi i opopona, ina elentiriki, omi ero, ero ibanisoro
- Faaye gba awon ileese olokowo lati da ise sile
- Pese awon omowe olopolo pipe lati awon ile eko wa, akedemi aye, fasit, poli ati beebee lo

**KI A LE ARUN WOLE (KARAOLE)**

**Isipaya Wa: Gbigba awon eyan wa lowo iku ojiji ati arunkarun ti ijamba oko, ailowolowo ati ile iwosan ti ko muna dodo n se okun fa**

- A o se eto ilera to fie se mule daa daa, paapaa fun awon omode, obinrin ati agbalagba
- Eti ilera to muna dodko fawon ara ilu
- Ipese oko gbajare fun awon ti o ba ni ijamba oko loju popo abi orisi ijamba mii
- Ipese ile iwosan ti awon onisegun oyinbo ni ibuso kilomita mewaa-mewaa si ara won, yika Ipinle Osun
- Bakan naa ni a ma si awon ile iwosan gbogbogboo yika Ipinle Osun ni ibuso kilomita ogun si ara won

- Ipese awon ile iwosan ti a ti ngba awon alaare ti apa ko ba ka ni awon ile iwosan wewe ni ibuso kilomita ogbon sira won
- A o se eto odanilekoo ti yoo mu ki awon osise ilera wa ma a goke agba lenu ise won, eyi ti yoo je amoriwu
- Bakan naa ni a o se atileyin fun awon eto ilera latara Isegun Ibile

**INA OBA (ELENTIRIIKI)**

Ipese ina elentiriiki si gbogbo ilu ati ileto lo je akoso Ijoba egbe oselu AC logun ni Ipinle Osun

- A o r ii pe oba gege  bi ohun amusagbara wa fun ilo awon eniyan wa ninu ile, lenu owo ati nileese won gbogbo
- Awon ileese aladani ti ise won ba jemo oro ina oba ni ijoba yoo fi aaye gba lati da ileese yi sile ni Ipinle Osun

**AABO**

Ipese aabo fun emi ati dukia awon ara ilu lo se Pataki si wa. Ijoba wa yoo gbe eto pataki kale fun awon Oloopa ati ajo awon egbegbe idabobo awujo

Yoo se ipese owo iwuri pataki fun awon osise eleto idabobo to ba n sise ni Ipinle Osun lati le fi ran ise won lowo

**ILEESE PANAPANA**

A o mu ki ojuse ileese pana-pana wa tubo dara sii i, lona ti itakiji won si awon isele laabi tubo ma ya kanmo-kanmo lasiko pajawiri

**KI A KEKO TO SE ANFANI**

***Isipaya wa: Igbogun tie dun awon odo nitori eto eko ti ko le fun ni ni ise se***

Lati le ripe eto yi waye, ijoba waa yo

- Se eto eko ofe to wulo fun ara ilu
- Dojuko eto eko ti yoo je ki eeyan wulo fun ara re ati awujo
- Se afikun si awon nkan iwuri fun awon Oluko, ati lati se ise pelu ajo awon Oluko lati da awon Oluko pada si ipo iyi ati eye won
- Se atunto eto isakoso awon ile iwo, a o si ma yan awon Oluko si ipo Akeko  Agba yan-yan ti a mo si Akowe Agba larin won
- Tun gbogbo ile iwe se a o si pese awon ohun idanileko pelu awon ibi ikawe
- Ri si ifowosowopo awon Oluko ati obi lati le rip e a fi eko to ye koro ko awon omo wa
- Se agbekale awon ajo ti yoo ma ri si oro ile iwe
- Se eto oranlowo ile kiko fun awon Oluko ti won fe ko ile si ilu won
- Ripe awon omo ti o wa ni kilaasi ikawe kop o ju
- Se eto eko agba to yanju
- Da awon ile eko sile ti a ti ma ko awon eeyan ni eko ati ise ti won yoo le fi sise ati gbe aye iderun (akademi aye)

**ILE EKO GIGA ATI EKO UNIVERSITY**

A maa ri daju pe ile eko giga yunifasiti Ipinle Osun bere laisi idiwo atipe eto eko re fidi mule danindanin peli ifowosowopo awon ile eko giga nla to wa loke okun

**KI AYE DARA FUN GBOGBO WA(KODARA)**

**AKOSO IJOBA ORE ARA ILE**

Ijoba wa ti pinnu lati r ii pe, awon arailu, ati Ijoba gbora won yekeyeke nipa mimu ki awon ara- ilu maa mo ohun ti Ijoba n se lese- ese

**IGBIMO AWON AGBA (EGBE AGBA)**

Ijoba wa ma ma gbamoran lodo awon egbe agba gbogbo ladugbo kookan nipa idagbasoke ati ilosiwaju ilu

Ipinle Osun ni olorun fi awon ojogbon olopolo pipe sike to je pe won ti rin kaakiri agbaye, sugbon ti Ijoba ko fun laaye lati lo ogbon ati iriri won lateyinwa. Awon agbaagba yii ni a maa ba, lati mu ki won ma gba Ijoba wa nimoran, nitori agba k ii wa loja kori omo titun wo

**EGBE ODO**

Ijoba wa yoo faaye gba imoran odo awon odo. Awon odo ni won po ju laarin wa sugbon o seni lanu pea won Ijoba latehinwa o ka won kun

Ijoba wa yoo ma a gba awon egbe agbegbe kookan laaye lati ma yannana awon isoro iyowu to ba ri dojuko won

**ERE IDARAYA**

Ijoba yoo mu oro idagbasoke awon are idaraya lokunkundun ati ipese eroja ere idaraya gbogbo naa si awon papa isire wa

**ATUNTO SI ETO IDAJO**

Akoso Ijoba to moyanlori ni Ijoba ti kii figba-kan-bo-kan ninun, ti kii fie to awon ara ilu dun won eleyii ni akoso Ijoba wa maa mu lokunkundun nipa riri i daju pe won o fi iya je enikeni labe ofin, won a tele ohun ti awon amofin ba pa lase

A o sagbeyo eto liana idajo titun (ADR) to da lori eto igbajo ofe fawon mekunnu

A o safikun si owo ajemonu awon osise amofin ati awon adajo. Bakan naa ni a o pese awon ohun eroja igbalode sawon ile ejo wa gbogbo

**ETO IBANISORO**

Ijoba wa, yoo satunto si ile ese ajo ongbohun safefe Ipinle Osun OSBC lati je ki:

Ojuse re tubo jafafa s ii, ki awon osise re si danto lenu awon eto alarinrin won

A o pese awon irinse ti ode oni lati r ii pea won ile ise ongbohun safefe wa duro deede bi ti awon elegbe won kari aye

**IDAABOBO AWON ARA ILU LORI OJA RIRA**

Ko ye ki awon ara ilu maa na owo gegegee lori awon oja ati dukia ti won ba nfe, tayo awon elegbe won kari aye

Ijoba wa yoo sowopo pelu awon ajo ti o ni erongba kan na pelu ijoba lati dekun ireje lori oja rira

Abalo-ababo, mo ma pese akoso ijoba ore ara ilu, eyi ti ojuse re ma a je ijoba awarawa, ara otun, tiwa-n-tiwa

Ibo yin ni yoo gbe mi dori aleefa lojo kerinla osu kerin odun yii(2007) lagbara Olorun

Emi k ii se oni-makanruru to n ji ibo onibo, nitori naa e jowo e jade, e dibo, e si daabo bo ibo yin ki e ma je ki won gba eto yin lowo yin

Ma se ta ibo re fun awon ajegudu –jera ti won ki i pon omi sile di orugbe

Bi o ba je ki won tun tan o je, gbogbo wa lama wa ninu iya oun ise ati aisi ibale okan fun odindi odun merin gbako

E dibo yin fun emi omo yin, Raufu Aregbesola, emi ati awon emewa mi yoo fi otito inu sise kara-kara lati maye derun fawon ara ilu

Nigba to ba maa fi di odun 2011, e o ti r ii pe, awon omo yin ti ni eko to ye kooro, awon odo ti ko ni ise lowo yoo ti rise se, awon agbe ati awon onise owo pelu awon onisowo yoo si ma fope fun Olorun. A o si le e ma pese onje lajeyo ati lajeseku fawon eniyan wa ni Ipinle Osun

Pelu ifowosowopo yin, akoso ijoba mi ma a sa ipa wa lati maye derun bi tatijo ti jije mimu po repete nile wa, ki o to di odun 1962

*Agbajo owo la fi nsoya*

*Oluwa Olorun a ti wa leyin*

*Oodua a fun wa se*

*Eke ki a le ise wogbo*

*Ka le osi sonu*

*Kaye dara fun wa tomo-tomo*

E fi ibo yin so mi di Gomina lojo kerinla osu kerin odun yii, 2007

E gba ijoba ise, osi ati iya kuro lori aleefa, e gba ise oun iya kuro lawujo wa, lagbara Oluwa mo ma fi ohun gbogbo ro yin lorun

*Eyi ni majemu mi,pelu eyin eniyan mi ni Ipinle Osun*

*E je ki a se e bi won se nsee*

*Ki o ba a le rib o se nri*

ORANMIYAN OMO OODUA DE FUN AGBE, AKOWE ATI ONISE OWO. ARIN NA KO RE AKOYA IBI

KI A JUMO SE ASEYORI

E DIBO FUN AREGBESOLA

E DIBO FUN AC

ISE DEEDE, ALAAFIA ATI ILOSIWAJU

LAGBARA OLUWA, AWA LA O BORI